# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 952 LAGOS SATURDAY DECEMBER 19 — DECEMBER 25 1964 KỌBỌ MEJI


# Nwon Lu Oba Kan Nwon Fa Ewu Re Ya Won Si Gba Ade Ori Re

AKURẸ — Awọn Ọlọpa Nigeria ni ilu Akurẹ nwa awọn ọ-unr n gba bara meji kan awọn ti awọn lu Ọba ni ile onjẹ ni ilu Akurẹ ni ọsan ọjọ ketad nlogun oṣu yi,

Ologbo ti ilu Igbo Ọba L.O. Mafin ṣebi lati iha Okit pupa ni ipinle iwọ Orun ni a gbọ wipe o lọ jeun ni ile onje. Nigbati Oba yi np da bọ wa si ile, awọn ọkunrin meji yi da mato rẹ duro gẹgẹbi ẹniti o fẹ bere iranlọwọ.

Bi mato Ọba y ti duro, awọn ọkunrin yi wọ Ọba na jade uro ninu mato re nwọn si b rẹ si ko igbati bo, nwọn lu pupọ nwon si ṣi Ade ori re lọ. Nwọn tu ẹwọn alanjatu a fi golu rọ ni ọrun Ọba na; gbogbo owo ti o wa ni ọwọ re ni nwọn gba.

A gbọ wipe nwọn lu nwa mato Ọba ati ọkunrin kan ti o joko t. Ọba ninu mato ni aluki. Larin rogbodiyan yi aṣọ ti Ọba wọ ya jalajala


## LAGOS RACE CLUB

IPADE ERE ẸṢIN FUN OṢU DECEMBER 1964.

Ere Ẹṣin yio bẹrẹ ni ọjọ wọnyi -

Sunday December 20th, 27th, 1964 ati ni oṣu January 1964, ni Friday 1st, Sunday 10th ati 17th.

Agogo mẹta abọ (3.30) ọsan ni awọn ẹṣin yio bẹrẹ si sa ere ije ni awọn ọjọ ti a to si oke iwe yi.

ASỌTẸLẸ

Eto siwaju ere ẹṣin yio bẹrẹ ni agogo kan abọ si meji ọsan ninu ọfisi Akọwe ẹgbẹ ni ọjọ ipade ere ẹṣin ni Ọdan l'Eko.

OWO IWỌLE

Ṣile mẹrin ni owo iwọle ni ọjọ kọkan pẹlu owo iworan.

AWỌN ỌMỌDE

Awọn ọmọde ti ọjọ ori nwọn ko ba to ọdun mẹrinla ko ni ẹtọ lati wọ inu ọgba nibiti ẹṣin gbe nsa re.

ORIRE

Tita ati pipin owo orire yio wa ni ọjọ kọnaa ti nwọn ba se ipade ẹṣin nọmba ti wa ninu iwe iwọle oniṣaluku ni yio fi han bi ẹnikan ba jẹ owo, Ẹni kinni yio gba £2: 10/- ẹnikeji yio gba £1:10- ẹnikẹta yio gba 10/-.

AWỌN ẸṢIN TITUN

Awọn ẹṣin pataki yio ti ipinlẹ Ariwa wa si ipade yi, Ẹ ma wo ao pin owo ribiribi.

C. A. CHAGOURY
HON. SECRETARY


# Ore Meta Ti Nwon Ko Ya Ara Nwon

Nigbat eyi owu awi pẹlu iyawo rẹ ati ọmọ re pa da de ile lati oko, nwọn ba okunrin mẹta kan n e u ọna nwọn eyi owu awi ki awọn awọn na si dahu dar dara. O ṣi ilẹkun o wọ inu ile, iyawo ati ọmọ rẹ na tọ lẹhin. O ke si awọn alejo yi pe ki nwọn wọ ile wọn si wọ ile.

O bu omi fun nwọn pe ki nwọn mu, lẹhin na o si bere pe ni bo ni nwọn lọ ati ni bo ni nwọn ti mbọ. Awon alejo na dahun pe ilu awọn nna pupọ ati pe awọn ti fi ile silẹ to oṣu mẹfa, ilu bayi bayi ni awọn si nlọ. Nitorina awọn bẹbẹ ki o jẹ ki awọn simi ọjọ mẹta nihin.

Eyi owu awi ki nwọn ku irin ati iforiti o ni ki iyawo lọ fi su kana fun awọn alejo lati le jẹ onjẹ ti o dun lati ukan b oṣu mẹfa ti nwọn ti fi ẹsẹ sin igbo bọ Iyawo t gun iyan gbigbona pẹlu ọbẹ ẹf o to n nkan elo inu fun awọn alejo ati fun ara nwọn.

Nigbati o di ọjọ kẹta awọn alejo yi dagbere pe

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

# ELETI – OFE

(A NIU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME

28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-OFE" Lagos

P. O. Box 467, Phone 23370

VOL. XIV NO 952 SATURDAY Dec 19 - Dec 25 1964


ORO OLOTU:

# E Ku Ipalemo Odun 'Keresi

A ki gbogbo ẹnyin ọ awe ati gbogbo ara ilẹ Ni- ¡eria wpe ẹ ku ipalẹmọ ọdun Keresi, Oluwa ko jẹ ki ki ọdun na ṣe oju ẹmi wa ni agba ati ni ewe, ni ọkuu- rin ati ob nrin. Ki Ọlọrun jẹ ki ọdun na ya abo fun wa.

Ni igba laiai ti ọdun yi ba wọle awọn oni'u a ma la ilu bayi pe "Keresi mesi ọdun de ọdun Olowo." Awọn ẹlesin ‹ir yo nwọn si ma jo nwọn a ma yọ pẹlu awọn ẹni ọre ati alabagbe ti nwọn jẹ ẹlẹsin miran.

O jẹ nkan iya ni lẹnu lati ri wipe ọdun na yi biri ni iwọn ọdun di sẹhin, ko da bi ti atijọ rara ti a nfi ọti ati nkan adidun jẹ igbadun rẹ. Nisisiyi Kuma, igo ọbẹ g gun ati ki a na ara ẹni ni paṣan ni nwọn fi nṣe ọdun na.

Ọdun yi jẹ iranti ọjọ ibi Jesu ti awọn Musulumi npe ni Y sa. O si ye ki gbogbo Kir yo ati Musulumi ṣe iranti ọjọ ibi na gẹgẹ bi a t nṣe iranti ọjọ ibi ti ara wa ati ti awọn ọmọ wa.

Nitorina a gba yin ni imọran pe ki a ṣe ọdun na ti ọduu ladan ati ayọ ni irant ẹni Ọ.ọrun t njẹ Jesu. Ọlọrun ko fi ọpọlọpọ ọduu han wa. Amin.

---

# Olukoni Fi Iwe Madaru Wo Ise

IJẸBU-ODE Ọdọmọkunrin kan ti a gba si iṣẹ Olukọni ni College Odutọla ni Ijẹbu-Ode ti owo oṣu rẹ si jẹ

( Wo yoku loju ewe karun )

# Igbesi Aiye Anobi Mohammed

Lati Ọwo Alhaji T. K. Oshishi

Nigbati Anobi di ọmọ ọdun mẹrin a da pada fun iya rẹ ni iya rẹ pinnu pe on yio gbe ọmọ na lọ ki awọn ẹaja on i ilu Medina.

A gbe Anọbi lọ ki awọn ẹbi iya rẹ ni ilu Medina awọn ẹbi iya rẹ si yọ mọ wiwa Ami̧not pẹlu ọmọ. Nigbati iya Anọbi ndari bọ lati madina pada si ilu Mecca, titan de si ni oju ọna o si ku a npe nyi ibi ti a sin oku iya Anọbi si ni Abuwa ni agbegi e Medina.

بسم الله الرحمن الرحيم

Obinrin kan ti oruko rẹ ijẹ Hamuimuna ni o mu Aọbi wa s i i Meka lọdo Baba-baba rẹ t a npe ni Abudu Mutalib. Anọbi di ọmọ ọdun mẹfa.

Baba re agba fẹran rẹ o si ni anu rẹ l'ọkan ti baba agba fi ku nigbati Anọbi papa di ọmọ ọdun mẹjọ. Abudu Mutalib si ti sọ asọtẹlẹ Anọbi fun aburo rẹ ti a bi le ti a npe ni bu Abu Talib.

Lẹhin iku baba rẹ agba Anọbi ngbe ile aburo baba baba rẹ fun itọju gẹgẹbi asọtẹlẹ baba rẹ agba Talib fẹran Anọbi nitori iwa pẹlẹ rẹ ati wipe ki iṣe ere gele ti awọn ọmọde nma ṣe o fẹran rẹ pupọ dipo ti o ṣe pe ko le jẹun laiṣe pe o ri Anọb.

Nigbati Anọbi di ọmọ ọdun mejila o ba baba rẹ Abu Talib lọ si irin ajo owo ṣiṣe si ilu awọn Kọra nigbati nwọn de ilu ti a npe ni Busary on ni ẹnu odi ti o jẹ ọna ti gbogbo enia ngba wọ ilu ni ẹnu ilẹ Larubawa. Ọkan ninu awọn Alufa NOSARA (MONK) wa pade nwọn ni ọna oruko rẹ a ma jẹ Baheerun. Lati ori oke pẹtẹsi rẹ ni o ti ri Anọbi nigbati nwọn bọ.

(Wo yoku loju ewe karun)



Alhaji T.K. Oshishi

# Olopa Ibile Fi Ara Pa Nibiti Ina Ti Njo

MUSHIN — Ọkan n'nu awọn ọlọpa ibilẹ ni ilu Mushin fi ara pa nigbati o lọ ran nwọn ni ọwọ nigbati ina njo ile kan ni ile karun ni orere Itirẹ ti iyana Mushin. Ọlọpa na wa ni ile iwosan ni ilu Ikẹja.

Irohin alafi oju ri sọ fun wa wipe awọn nkan ini ti o ṣe ofo ninu ina yi nlọ bi iwọn o ni ẹgbẹrun mẹrin pọun. Iya ti o ni ile pẹlu awọn ti nwọn gba ile ni ọwọ rẹ sa asala ẹmi nwọn nigbati ina bẹrẹ nwọn ko si ri kinikan mu jade ju aṣọ ti o wa ni ara nwọn lọ.

Ọkan ninu awọn ti ngbe ile na arabinrin Fẹla Banjọ sọ wipe, o ni lati je wipe inunibini enia kan ni o da ina sun ile na, nitoripe ina na ko ṣẹlẹ lati inu ile wa.

O ni ọkunrin kan ti nre koja lọ ni o se akiyesi ina na ti o njo lati ori orule, ti o si ke igbe Ina! Ina!! Ina!!! ki awọn to le fura lati sa asala fun ẹmi awọn.

Nwọn ka r aye mu nkankan ninu nkan ini nwọn nitoripe ina na ti gbilẹ pupọ ki nwọn to ṣe akiyesi pe ina njo.

## Iya Pelu Omo Re Ku Iku Jamba Mato

[illegible]

UDI — Iya kan pẹlu awọn ọmọ rẹ mẹji ku ni ọsẹ ana nigbati mato ti nwọn wa ni inu rẹ fi ori gba ori pelu mato imiren.

Awọn ti wọ ku ni Mrs Marcilina Ekwe ọmọ ọdun mejilelọgbọn, Gilbert Ekwe ọmọ ọdun mejilelogbọn ati Chidobẹ Ekwe ọmọ ọdun mejila. Nwọn pada bọ lati Umala ni agbegbe Orlu nibiti nwọn gbe ọ ṣe isin nigbati awọn fi ọmọ Marcilina obinrin je Alafa ninu ijọ awọn Padi.

A ko awọn ti awọn fi ori pa ninu mato na lọ si ile iwosan ni Enugu fun itọju.

# Oko Oju Irin Danu

IWO — Iṣẹ ọkọ oju irin yio fa şi ẹhin diẹ i p-ọ iwọ oruo nitori ọkọ ẹru kan ti o ṣubu u a in Iwo ati Odo-Ọba.

O to awọn wagọnu ẹru olowo iye iye mẹsan ni wọn takiti si inu odo-ọba nigbati ọkọ oju irin ti ọkọ na rin lọ o danu.

A gbọ pe ko si ofo ẹmi ju wipe awọn ẹru olowo iyebiye ti wagọnu ẹru ṣe ofo pupọ.

# Awon Asoju Igbima Ibile Ja

ONITSHA – Awọn asoju igbimo ibilẹ ti ilu Onitsha ja pẹlu ara wọn ninu ipade pajawiri kan ti nwọn pe ni ọsẹ ti o koja.

Nwọn bẹrẹ si ju aga ati tabili fun ara nwọn, gbo gbo apamọ iwe ise Council ni wọn bajẹ patapata nwọn si bẹrẹ si bu ara nwọn ni ikọn ko jọ kan.

Awọn ero ti nwọn wa wo ran bẹrẹ si bo bo nwọn nigbati awọn osoju miran jade lati wẹ ijakadi pẹlu ara nwọn ni.

# Won Lu Obinrin Pa

AGBANI — Awọn ọlọpa Agbani bọ si Inu damudabo ninu ọsẹ ti o koja nigbati nwọn ri gbọ wipe obinrin kan ti oyun nu rẹ ṣẹṣẹ di oyun oṣu mẹrin ni nwọn lu pa nigbati nwọn ja ija ẹbi.

( Wo yoku loju ewe kerin )

# Ejo Apania Lo Si Kotu Nla

IBADAN - Adajọ agba ti o joko si k o t u giran ni ilu Ibadan ti bẹrẹ s gbo ẹsun ti awọn ọlọpa mu wa ni pa ojo sule, ọkunri ti nda na buredi ni orere Yemo ti n ni agbegbe Adeọyọ ni Ibadan,

Nwọn fi ẹsun kan ọ ọ Sule pe o pa obinrin kan ti nta ẹmu ni orere Yemoja ninu oṣu keje ọdun ti a wa yi obinrin na nje Abigael Asuake.

Ọkan inu ẹlẹri a w ọ n ọ l ọ p a Humuani Oyinade Aoẹkẹ ti nta epo pupa sọ fun kotu pe nigbati on rekoja ni ọna ẹnu ọna iyara ọdaran yi ni ọjọ ti nkan y sẹ e o ... ẹṣun rẹ ... iti p a, nigbọ ... o n gburo ija ninu iyara.

O ni on lọ sọ fun baba onile pe on ṣe akiyesi pe nwon ja ninu ile rẹ ariwo ija na si ga ju nkan ti ... oju kuro fun lọ.

Ogbẹni Lawani Oyebode ti se baba onile sọ ni kotu nini ẹri rẹ fun awọn ọlọpa pe ni ọsan ọjọ ti okan yi ... obinrin ti a npe ni Oyinade Aoẹkẹ wa sọ fun on ... ja ni ... nu ile on, ... on ... aburo on lọ pe ọlọpa.

O fi han kedu pe nigbati on de bẹ ni ọj kej on ba oku obinrin ilẹmu yi ninu iyara.

(Wo yoku loju ewe kerin)

# Onisowo Kan Yi Iwe Ijoba Pada

KADUNA – Ọgbẹni John Kawo ti ṣe ọmọ ọdun mẹrindinlọgbọn ni Onidajọ awọn ọlọpa sọ si ẹwọn oṣu merin fun ẹṣẹ pe o ṣe eru.

Awọn ọlọpa fi han kotu pe John Kawo yi iwe itaja ti ijoba fun o fi si inu iwe na wipe on ni aṣe lati ma ta oja tete. ọlọpa si fi han kotu pe ko si eni ninu aṣẹ itaja ti nwọn fun.

Kawo sọ fun Onidajọ pe on ko mọmọ se bẹ, nitorina on bẹ onidajọ ki o da ori jin on. ṣugbọn onidajọ ni ki o lọ ṣe ẹwọn oṣu mẹrin pere.

## Olopa Ti Awon Janduku Mole

AKURE – Awọn enia metadinlogbọn ti awọn ọlọpa pe ni awọn ọmọ janduku ti ẹgbẹ ọṣelu ni a ko wa si iwaju Onidajọ awọn ọlọpa fun ẹsun pe, wọn ri awọn nkan ija bi ibọn ti arọ ni ile wa ati ọpọlọpọ igbo ni ọwọ wọn.

Ọga awọn ọlọpa to gba okun nla Ọgbẹni Lawal Ali sọ fun adajọ pe awọn ko nwọn oku ria yi ni Ondo nibiti awọn gbe nda gruba awọn ọmọ ẹgbẹ ... ko pe ti wọn.

O fi han kotu pe ọpọlọpọ ada, ọbẹ, ibọn awọn ogun baruku ati igbo ni awọn ri gba ni ọwọ awọn.

Awọn ọlọpa ni ọkan ninu wọn Ajewole Ake ni a tun nu ẹsun re wa lọtọ pe o yọ ada si obinrin kan ti a npe ni Falilatu Karimu pe on yio pa, a si tun gba ọpọlọpọ igbo ni ọwọ rẹ.

## Ejo Apania Lo Si Kotu Nla

( O bẹrẹ loju ewe kẹta )

IBADAN— Ojo Sule, a van Buredi kan ni ilu Ibadan sọ fun Onidajọ agba ni ọjọ Monday wipe on ko mọmọ pa iyawo on ti ologbe Abigael Ashakẹ.

Sule nsọ idi ọrọ tirẹ ni iwaju adajọ, O ni nkan oṣu keje ọdun yi, o ni on pelu iyawo on jẹwun lọwọ ọkunrin kan ti a npe ni Adekayaoja wọ ile wa pe iyawo on wipe ki o wa ba on lọ si ode kan.

Sule ni on mọ ọkunrin Adekayaoja yi ni ore iyawo on, O ni iyawo on dide lati ba ọkunrin na lọ, ṣugbọn on ko gba. O ni nigbati on ko fun iyawo on pe ko gbọdọ lọ ijiherẹ larin on ati Adekayaoja o ni nibiti

(We yoku loju ewe karun)

# Olopa Gba Ibon Ati Ota Lowo Awon Janduku

IBADAN — Awọn ọkunrin Ibo merin kan ti oruko wọn nje Solomon Bobi, Effiong Umoh, Bassy D vid ati Samuel Agbiri ni a ko wa si iwaju adajọ awọn ọlọpa ni ilu Ibadan fun ẹsun mẹta.

(1) Nwọn ri nkan ija ninu ile wọn.
(2) Nwọn ri ewe igbo ninu ile wọn
(3) Nwọn ri dajị igo oti Oloro ti a mọ ọpọ mo gbo.

Awọn Ọlọpa ri awọn enia yi ko ni adugbo ti okola ni ilu Ibadan nigbati awọn ọlọpa nṣe abẹwo awọn ile kakiri ninu oṣu ti o kọja. Awọn ọkunrin na ni awọn ko jẹbi.

Ọgbẹni Samuel Bẹwaji ti awọn ọlọpa nu sọ fun Onidajọ pe ki o ma ṣe fun wọn ni iduro nitori awọn ọlọpa ri nṣe ode ibọn ati ọta tabi awọn nkan ọṣẹ ninu ilu Ibadan ati aroko rẹ.

O ni ki kotu ṣe akiyesi awọn ẹjọ a fi agbara ja ni l'ole bi o ti pọ to ni ilu, a ni papajulọ igba iduro awọn nwọnyi yio di iwadi ti awọn ọlọpa nṣe lọwọ.

## A Fi Ewon De Mighty Joe Wa Si Kotu

EKO — Isiaka Busari ẹniti alaje rẹ nje 'JOE Alagbara ni a nu wa si kotu ọlọpa fun ẹsun pe o lu oku ti iohn nipa ṣiṣe Ọgbẹni Ayo Williams ni ese ni ile oti Lido ni ilu Eko.

Ki nwọn to le mu Isiaka wa si Kotu awọn ọlọpa de ni ẹwọn ni ẹsẹ nwọn si tun fi ṣẹkẹṣẹkẹ de ni ọwọ.

Oga Ọlọpa Ọgbẹni U.A Opuene ti ṣe ẹnu fun ijọba ke si Adajọ wipe ki o ma gba iduro fun ọdaran yi. o siyẹ kinwọn fi pamọ ni asiko damu dabo yi.

Ọgbẹni Upuene ni awọn ọlọpa nwa ọdaran yi ni iwọn oṣu diẹ kọja si awọn to ri mu ni ile oti Lido. O ni ọpọlọpọ ẹjọ ni o wa fun ọdaran yi. O to iwọn iwe ifi ọba mu mefa ti awọn Adajọ ni erisirisi ti fi ọwọ si pe ki nwọn ma wa.

Adajọ ni ki a fi pamọ si ọgba ẹwọn di ọjọ karun oṣu kini ọdun.

## Nwon Lu Obinrin pa

( O bẹrẹ loju ewe kẹta )

A ri gbọ pe awọn ọlọpa ti lọ mu ọkunrin kan ọmọ ọdun mejilelọgbọn ti o jẹ onisowo nipa iku obinrin na.

Nwọn ni ija yi bẹrẹ lori wipe obinrin yi ko ṣe dodo pelu ọkọ rẹ.

# Ejo Apania Lo Si Kotu Nla

( O bẹrẹ loju ewe kẹta)

ti gbe dimu Ade oyaoja ri ada ni koro ti on lo si o he ada lati fi ṣa on, ṣugbọn on ki pẹlu ada on si gba ni ọwọ rẹ.

O ni on fẹ fi ada na ba ọrẹnikoj on ja, ṣugbọn Adekayaoja tari iyawo on s on ni ada ba iyawo on. O ni on ko le mọmọ pa iyawo on tabi ki on ṣa ni ada bi ko ṣe wipe ọkunrin Adekayaoja tari rẹ si ọwọ ada.

# Olukoni Fi Iwe Madaru Wo Ise

Poun metadinlogọta ati ṣile mẹdogun £57:15:0. ni a gbọ wipe onidajọ ju si awọn odu miran nitoripe iwe Madaru ni o fi wo iṣẹ.

Ọkunrin ti oruko rẹ nje George Beresibo sọ fun adajọ pe on jebi lori ẹsun mẹji ti awọn fi kan on ni iwaju rẹ. O ni ki adajọ fi ori jin on nitoripe on ṣe madaru yi lati fi ri iṣẹ ni.

Ọgbẹni Leonard Chukwu sọ fun adajọ kotu pe ni iwọn osu keji sẹhin Beresibo kọ iwe iwa ṣẹ si College Odutọla fun iṣẹ olukọni.

O purọ pe on ni oye R S A ipo kẹta ninu awọn iṣẹ ẹkọ Iṣowo o ni on gba oye B.A., B.sc, M.A., ati M.Sc ni ile ẹkọ giga Cleveland, Ohio ninu ede gẹsi ati bẹbẹ.

O ni nigbati Olukọni agba ni ki Beresibo lọ mu ojulowo iwe ẹri rẹ wa, o tọrọ aye wa si Eko lati wa mu. Nigbati o mu de oluko agba ṣe akiyesi wipe iwe madaru ni, o sọ fun awọn Ọlọpa. Awọn ọlọpa lọ wo ile Beresibo nwọn ba ogun iwe ẹri madaru ni yara Beresibo.

# Awon Oloye Eko Binu

EKO — Awọn aglaaju ninu awọn Oloye Eko ko eto i awọn a fi obaje mẹrin ṣe nipa pe nwọn yio da ifa lati fi han ọba Eko larin awọn idi mẹfa.

Eleti Ọfẹ Ọlọye Ishola Bajulaiye sọfun wa wipe lẹhin ipade awọn afi ọbaje mẹrin, o ni awọn da ifa ninu agbala ... lati yan ọba titun fun ara Eko.

Awọn idile mẹfa ti awọn mu oruko enia kọkan wa ni idile Akisemoyin, Esinlokun Akitoye, Adele, Ologun Kutere ati Oluṣi.

Awọn yi ni enisi idile kọkan fa sile lati da ifa le ni ori

(Wo yoku loju ewe kefa)

# Arikogbon Owe Gesi Ni Ede Yoruba

1 Ti a ba tete ... a ṣọ ti o ba faya a ma dun mọ aṣọ pipa ninu.

2 Igba ti gbe lo, o si ti pa ọpọlọpọ ipọn run.

3 Omugọ enia ... ve ki o ma sọ odi ... asiko ti ko to.

4 Ti o ba mbi ... ka eni ti ti de ọgọrun ... to sọrọ. To ba ... e wipe o binu si tobi ... da ... ẹgbẹ run.

5 ... ṣe duro de iulasi ki o ṣe isa fun iṣẹ rẹ.

6 Gbogbo asiko lo dara fun ọkan ma ṣe sọ asiko kan nu.

6 Iro ori wo ni iṣẹ ti o le ju ṣugbọn enia diẹ ni o ma fi ... se ṣe

8 Ẹniti o ba mu ṣibi dani yio bu ọbẹ bi o ba ti wun

9 Ọrẹ ti yio ba o de ọrun ni eyi ti o ba fi ṣe itọrọ anu.

10 Ti Kiniun pẹlu ọmọ Aguntan ba jọ dubulẹ o daju pe Kiniun ni yio lọ sun.

11 Ma ni ero pe iwo le yi enia ni ọkan pada lai jẹ wipe iwọ na ti yi ara rẹ ni ọkan pada.

12 Bi o ba fẹ ki o wo oye ki o to bẹ, ṣugbọn ti o ba ṣe pe o fẹ be ni ma ṣe bẹ ju

# ...besi Aiye Mohamed Anobi

(O bẹrẹ loju ewe ...)

Nigbati o de ọdọ nwọn o ri wipe Anobi ti Muwsay ati Iyisay ti sọ ọrọ rẹ silẹ ni yi o pe baba agba o ni ṣe pẹlẹ o. Toju ọmọ yi, enitị o ni iṣe ṣe fun ọlọrun ni ola ni enia ti o tobi ni nitorina ma fi silẹ nitori awọn Ju, nipa eyi Abu Talib ko duro pe ninu irin ajo na ti o fi mu Anobi pada si Makka.

A di Anobi Muhammed ni eda ti o pe; ọyin o ju rẹ funfun irun ori rẹ gun o si ṣan wa silẹ, iwo e ia rẹ fa enia mọra. Ni gbogbo igba a ma rerin musẹ o si rẹ ara rẹ silẹ fun gbogbo enia. Anọbi ko gun ... ni ko kuru, iwaju rẹ tẹrẹrẹ de, o si nwu gbogbo enia lati ma rini gbogbo igba.

Anọbi a ma ba enia jẹwọ a si ma ba enia sere, ṣugbọn ere ati ẹwọ ko sọ pe ninu iwa rẹ nitori ki fi asiko rẹ kan bi o tile ke e lo sere. Lati igba ... rẹ ki ṣe ere ki ṣe yẹyẹ ... ni ki si purọ. Abu Talib jẹri pe ni ọjọ ti on ti mọ ọ ko purọ ri. O ni ... tilẹ koria ija ti awọn ọmọde nma fi nṣe ere ni.

Ki a to bi Anọbi awọn Larubawa ko ni igba Olorun gbọ ju ki nwọn ma fi ori balẹ fun ere ati sigidi ti a fi owo ṣe Nigbati anobi ṣe ndagba ti o ri wa wọnyi o ba ọkan rẹ jẹ nu si ṣe pe awọn enia nwọny ti kuna nipa si sin nkan miran yatọ si Ọlọrun ti o da aiye ati Ọrun.

# Awon Olosha Da Onisowo Kan Lona

MUKURDI — Ọkunrin Onişowo kan ti ilu Jos ẹnitị orukọ rẹ njẹ Ọgbẹni Jame Umeh ni a gbọ wipe awọn ọlọsha dena de nị arin Gboko ati Makurdi.

Irohin fi han wa pe Ọgbẹnị Umeh npada lọ si ilu Jos, şugbọn nigbati o de ịbusọ mẹrinleiogun awọn ijọ Ọlọsha ti nwọn dịra ogun da mato rẹ duro nwọn ko awọn ẹru bị ọlọgota pọun ti mbẹ ninu mato nwọn sị tun gba pọun mọkanla owo wẹrẹ ti o şeku sị ni apo.

Awọn Ọlọsha na sọ fun pe ki o kuro ninu mato rẹ, nigbati o sọkalẹ tan awọn gba kọkọrọ ni ọwọ rẹ nwọn si wa mato na lọ. Ọgbẹni Umeh pada si Markurdị lati wa sọ fun awọn ọlọpa gẹgẹbi nkan tị o şelẹ sị oo.

Awọn ọlọpa nwa awọn ọdaran na şugbọn nwọn koi ti ri nwọn mu.

# Awon Ore Meta Ti Nwon Ko Ya Ara Nwon

(O bẹrẹ loju ewe kin )

awọn nlọ, şugbọn lati ọjọ ti nwọn tị de si ile Eyị o wu awi ni ikan ninu awọn alejo yi ti orukọ rẹ njẹ Suru ti da ọrẹ pẹlu ọmọ Eyị owu awi ti Oruku tiẹ na njẹ Suru.

Nigbati nwọn gbera ti awọn nlọ Suru kini ati Suru keji nsin ara nwọn nigbatị nwọn de ịbi ti nwọn ma pinya Suru alejo sọ fun awọn yoku rẹ pe on yio pada lati ma gbe pẹlu o oruko on.

Nigbati awọn meji yoku de ịbusọ ti ilẹ şu nwọn sị, nwọn ko le sun ọrọ suru ni nwọn bẹrẹ si sọ titi ịlẹ fi fẹrẹ mọ tan. Nigbati ilẹ mọ ẹnikeji ni on ko le dawa lai şe wipe on ri suru o ni on papa ntọ suru lọ.

Ẹnikẹta ni tị o ba ti npada lọ ba suru on na ko le duro ni on nikan lai sị tiẹ tabi Suru pẹlu mi. Bayi ni awọn alejo mẹta yị şe pada si ile Eyị Owu Awi.

Eyi Owu Awi bere pe şẹ ko si nkan tị ẹ tun fi pada si ibin Alagba nwọn dahun pe, emi ni agba nwọn orukọ mi a ma jẹ Owo, Orukọ enikeji mi a ma jẹ ọmọ oruko ẹnikẹta wa a ma jẹ Suru.

O ni latị ọjọ tị suru ti dẹhin si ịle rẹ nị awọn ko ti ni ifọkanbalẹ nitori pe lai ko si Suru pẹlu awọn awọn ko le da gbe, nitorina ni awọn şe pada wa sị ihahin lati wa joko pẹlu Suru.

Lati ịgbana ni Eyi Owu Awi tị di Olowo atị Ọlọmọ. Abule rẹ tị o şe wipe on pẹlu iyawo rẹ ati ọmọ rẹ ni nwọn gbe ịbẹ di ilu nla. Orukọ Eyi Owu Awi si tan ka agbaye nịpa Owo nini atị ọmọ bibi.

Printed and Published by The Union Printing and Publishig Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370.

ỌLOTU B. A. CAREW 43. Offin Road, Lagos

# Ojo Ibi Jesu Olugbala Ni Ibuje Eran Ni Bethlehemu

Ni iwọn ẹgba ọdun sẹhịn ni Maria Mundịya bị ọmọ ọkunrin si ibujẹ ẹran kan ni ilu Bethlehemu. Ọkan ni ọjọ na jẹ nịnu gbogbo ọjọ.

Nitotọ a bi ọmọ yị ni ọna ịyanu ki awa enịa aịye le fi Ogo fun Ọlọrun Ọba aiye. A gbagbọ pe Joseph Gbẹnagbẹna ti nşe anọ lati fẹ Maria koi tị da ana rẹ bele ki o fẹ wọ ile kị a ta ri oyun ninu ọmọ Mundịya yi.

Oyun ni arun ni nigbati o di oşu kẹsan onka şe ikẹwa Maria bi ọmọkunrin lai si iranlọwọ Adahunşe bẹni ko si asurepe onişegun, a ni ko si ẹnikenkan ni ẹba bi ti o ti bi ẹnọ ra ju ogo Ọlọrun lọ.

Awọn awo irawọ pẹlu owọn amoye ri irawọ ọmọ ni oju ọrun ni ọjọ ti a bi, nwọn si yin Oluwa ni Ogo. Olori awọn Alufa ijọna pe isin kiakia awọn ero si ti pe si inu ile Oluwa lati gbọ nkan ti Alufa Agba yio fun awọn ijọ

# Owo Olopa Ba Oni Wayo

BENIN Nị kotu ganran ni ilu Benin ni adajọ agba kan ti ju ọkunrin kan sị ẹwọn odun meje fun ẹşẹ pe o şe eru wọn si tun ba owo madaru ni ọwọ rẹ. Orukọ ọdaran na a ma je Fọlọrunsọ olofen,

Awọn ọlọpa ni nwọn ri owo bọlugi nị ọwọ rẹ pẹlu awọn nkan elo ti wọn fi nse owo pepa bọlugi ọdaran na si tun gba owo pọun metadinadọta lọwọ ọkunrin kan Sampson Igbịnosun ti nşe owo rubber wiẹe on yio sọ di ogoje pọun ati pọun mọkọnla fun ọgbẹni Igbinosun.

Ọgbẹni Igbinosun ni on sọ fun Fọlọrunsọ kị o pada wa fun owo na. O nigbati o ya Fọlọrunsọ ko awọn owo pepa maduru ati awọn nkan elo tị o fi nse wa ba on.

Nigbana ni o wa sọ fun wipe owo ni yi şugbọn on fẹ kị a lọ şe iwe nị office awọn alagbakọ. O ni ki on to sọ ọjọ ti yo pada on ti fi oro na han awọn ọlọpa, ọlọpa si ti de office awọn alagba kọ kị on pẹlu rẹ to de bẹ.

O nị nibiti awọn gbe nduna dura nị ọlọpa yọ sa awọn, o ni lẹsẹkan na Fọlọrunsọ gbe owo madaru ọwọ ju silẹ ati awọn nkan ti o fi nfẹ owo na ọlọ a ba mu,

Adajo ni on gba pe lo to ni o fẹ gba owo gidi lati fi owo madaru rọpo rẹ fun ọgbẹni Igbinosun ni torina ki o lo şe ẹwọn ọdun meje Pere,